# ÌWỌ NI ÀÁKÉ OGUN MI

# OṢÙ KARÙN-ÚN 2021

**Ìwé Mímọ́ Kíkà: Ìṣe Àwọn Aposteli 20**

**Ìjẹ́wọ́: Jerimaiah 51:20**

**ÌYÌN TÓ NÍPÁ**

1. Ọlọ́run, dide, kí o sì fàtu ohunkóhun tí a kò gbiǹ nínú orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyánu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyánu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti ìtẹ̀síwájú, síji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde kí o sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tó ń jí, tó sì ń wọ aṣọ ọlá mi, subú lulẹ̀ kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo àwọn tó ti mọ̀ ọ́n mọ̀ fi ara wọn sílẹ̀ láti dójú tìmí, gba ọfà ikú, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde kí o sì nù kúrò gbogbo ìpìlẹ̀ ẹkún kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
8. Ọlọ́run, dìde kí o sì fi mí ṣe ààké ogun rẹ, ní orúkọ Jésù.
9. Àwọn agbára ìpìlẹ̀ tí wọ́n ti fí mi sínú pàkúté wọn, fi mi sílẹ̀ kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
10. Àwọn agbára tó sọ pé lórí ìsòro ni mà á má a jẹun, ya wèrè kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
11. Ọlọ́run, dìde kí o sì fi mi ṣe ọ̀kan nínú àwọn aṣájú rẹ, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí ohùn rẹ gbọn ọ̀ta náà kúrò nínú àyànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, tú ètò ìsúná mi sílẹ̀ kúrò nínú ìdarí òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
14. Baba, fi ìpòǹgbẹ àti ebi ìwàláàyè rẹ fún mi, ní orúkọ Jésù.
15. Mo fi gbogbo ẹ̀mí àìlègbàdúrà bú nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, jẹ́ kí ayé mi pin àwọn ọ̀tá mi lẹ́mìí títí láé, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo pàkúté tí àwọn ọ̀tá ti gbékalẹ̀ láti jàmí lólè, túká, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo pẹpẹ sátánì, tó ń ṣiṣẹ́ ìránṣẹ́ lòdì sí ìgbé ayé ẹ̀mí mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ìrẹ̀wẹ̀sì àti ìlọ́wọ́wọ́ tí wọ́n ṣe lòdii sí pẹpẹ àdúrà mi, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ìdógò sátánì tó ń dí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mi pẹ̀lú ọ̀run lọ́wọ́, yọ́ dànù nípa iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
21. Baba, ràn mí lọ́wọ́ láti lè ní àkókò tó nítumọ̀ níwájú rẹ, ní orúkọ Jésù.
22. Ọlọ́run, jẹ́ kí gbogbo àwọn tó kórira mi, kí wọ́n pa ara wọn run, ní orúkọ Jésù.
23. Gbogbo ẹlẹ́rìí irọ́ tó ń dìde láti jẹ́ kí ogun mi pọ̀síi, kú, ní orúkọ Jésù.
24. Idà àwọn ẹni ìkà tí wọ́n ṣe lòdì sí mi ní ó máa gún wọn pa, ní orúkọ Jésù.
25. Àwọn agbára ìkà, tó ń bẹ àwọn tó lágbára jù wọ́n lọ, láti fi mí rúbọ, di gbígbémì nípa iná, ní orúkọ Jésù.

26. Orí ìkà òkùnkùn, tó ń fipá mú mi láti ṣiṣẹ́ nínú ìgbèkùn, ẹ̀san Ọlọ́run, dìde kí o gbé wọn mì, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo ìdábùú tí wọ́n gbé lé ìgbé ayé ẹ̀mí mi, di gbígbé kúrò nípa iná, ní orúkọ Jésù.
28. Ìgbé ayé ẹ̀mí mi kò ní wó palẹ̀, ní orúkọ Jésù.
29. Mo tún fi ayé mi jìn fún Ọlọ́run baba, Ọlọ́run ọmọ àti Ọlọ́run ti Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo ẹ̀mí àìfara-balẹ̀ níwájú Ọlọ́run, kú, ní orúkọ Jésù.
31. Gbogbo ẹ̀mí ìsún-àdúrà gbígbà-síwájú, mo gbé ọ dè, ní orúkọ Jésù.
32. Gbogbo panápaná òkùnkùn tí wọ́n yàn lòdì sí pẹpẹ àdúrà mi, di mímú so, ní orúkọ Jésù.
33. Baba, tan àbẹ́là mi, kí o sì tànmọ́lẹ̀ sí òkùnkùn mi nípa tẹ̀mí, ní orúkọ Jésù.
34. Àwọn agbára tó ń lo oúnjẹ ojú àlá láti pa ògo mi, Ọlọ́run, túmí sílẹ̀ lọ́wọ́ wọn, ní orúkọ Jésù.
35. Baba, fún mi ní ojú bíi ti Elisha, ní orúkọ Jésù.
36. Baba, fún mi ní etí bíi ti Sameul, ní orúkọ Jésù.
37. Àra Ọlọ́run àti ìjì Ọlọ́run, fọ́ ibi gìga ti òkùnkùn, kí o sì fún mi lómìnira, ní orúkọ Jésù.
38. Agbára yówù tó kórira àjọyọ̀ mi, Ọlọ́run, dìde, kí o sì dójú tì wọ́n, ní orúkọ Jésù.
39. Mà á kọ orin tí ọ̀tá kò fẹ́ kí n kọ, ní orúkọ Jésù.
40. Mà a jó ijó tí ọ̀tá kò fẹ́ kí n jó, ní orúkọ Jésù.